NATIONAL PENSION COMMISSION

*...Pension Guaranteed*

# Awon Oniruuru Ibeere

lori

# Ilana Idawo Ifeyinti Onipele Kereje

## Awon Oniruuru Ibeere lori ilana idawo ifeyinti onipele kereje

1. **Ki ni owo ifeyinti?**

   Owo ifeyinti je owo ti a maa n san fun eni ti o ti feyinti lenu ise loorekoore laitase nigba ti iru eni bee ba ti sise fun iye odun to peye labe ofin tabi ti ojo ori re ba ti de ipele ifeyinti tabi ti ailera ba pe iru eni bee n'ija ti ko si le se ise mo.

2. **Ki ni a n pe ni ilana idawo ifeyinti onipele kereje?**

   Ilana idawo ifeyinti onipele kereje je ona ti awon onise aladani tabi awon ti won n sise ni ile ise ti osise ibe ko to meta le gba kopa ninu Ilana ifeyinti olorananyan ajoda laaarin osise ati agbanisise ti ijoba apaapo oriile ede yii seto fun awon osiise. Eto yii maa n je ko rorun fun osiise lati ri owo ifeyinti gba nigba ti o ba feyin ti lenu ise tabi ti ara re ko mokun mo.

3. **Eredi ilana idawo s'apo owo ifeyinti onipele kereje?**

   Eto yii fi ni l'okan bale pupo, paapaa julo n'igba ojo ogbo, tori pe ni geerege ni owo Ifeyinti yoo maa wole si apo eni ti o feyin ti l'enu ise. Eto yii r'orun pupo, ko nira, ko si dojuru rara?

4. **Nje ilana idawo ifeyinti onipele kereje ti ni aseyori ni oriile ede miiran?**

   Bee ni, liana Ifeyinti Onipele kereje yii ti yori si rere ni awon oriile ede miiran bii Ghana, Kenya ati India.

5. **Iyato wo l'o wa ninu eto idawo owo ifeyinti olorananyan ajoda laaarin agbanisise ati osise ati ilana idawo ifeyinti onipele kereje yii?**

   Abe isakoso eto Idawo laaarin agbanisise ati osise ni mejeeji wa. Iyato t'o wa ninu mejeeji dale irufe ikopa t'o wa ninu mejeeji. Aigbodo ma se ni eto ikini je fun gbogbo osise.Osise ati agbanisise ti o kun oju osuwongbodo dawo si apo owo naa,ki osise le ri owo gba ti o ba feyinti tan.Sugbon ni ti Ilana Idawo Ifeyinti Onipele Kereje( Micro Pension Plan),ki i se orananyan,'wo-fun ni itelorun ni,eni ti o n dawo nikan lo kan.

6. **Iru eeyan wo l'o le kopa ninu eto ilana idawo ifeyinti onipele kereje eto?**

   Eni ti o n dawo s'apo Ilana Idawo Ifeyinti Onipele Kereje. O gbodo je

   a) Omo orile ede Nigeria ti ojo ori re ko din ni odun mejidinlogun (18 years);
   b) gbodo ni orisun tabi ona ti owo n gba wole;
   c) gbodo je olokoowo karakata, omo egbe tabi egbe akosemose;

d) le je eni ti o n da ise se (ise ara eni) tabi osise ile ise ti osise ibe ko to meta, yala won kowe gba a si enu ise tabi nipa oro enu lasan (ohun enu) ni osise bee gba wo agbo ise sise.

**7. Nje o seese pe ki enikan maa fi owo pamo si apo idawo ifeyinti miiran-? T'o ju eyokan lo?**

Ko seese. Apo idawo ifeyinti kan ni eniyan kan le ni ni ojo aye re.

**8. Nje eni ti o wa l'enu ise kan ti o si ti ni akosile eto ifowopamo owo ifeyinti le kopa ninu ilana idawo owo ifeyinti onipele kereje yi?**

Rara o, enikeni t'o ti n dawo s'apo owo ifeyinti olorananyan ajoda laaarin osise ati agbanisise ko leto lati kopa ninu liana idawo owo ifeyinti onipele kereje mo.

**9. Bawo ni mo se le ko'pa ninu ilana idawo owo ifeyinti onipele kereje?**

Eni ti o kun oju osuwon le foruko sile nipase eyiikeyii awon ajo eleto akoso owo ifeyinti t'o wu u. Eni bee yoo gba foomu (form), yoo f'owo si foomu ,n'igba naa, yoo gba foomu ifowopamo (RSA) ti eto ifeyinti. Eni bee le f'oju han tabi ki o fi ero ayelujara kese eto iforukosile ja.Leyin naa, yoo gba nomba (number) idanimo (PIN NUMBER).

**10. Bawo ni mo se le mo ajo eleto olusakoso owo ifeyinti ti o wu mi?**

Oruko ati adiresii (address) awon Olusakoso Owo Ifeyinti ti ijoba fonte lu wa ni oju opo weebu Ile ise to n sakoso eto ifeyinti gbogbo osiise ni Nigeria (PenCom) www.pencom.gov.ng

**11. Ta ni yoo maa se akoso ati amojuto eto idawo ifeyinti?**

Alakooso ajo owo ifeyinti, ti an pe ni PFA ni yoo maa se kokari eto akoso ati ifowo ifeyinti sowo ni oruko awon ti won n kopa ninu eto ilana idawo owo ifeyinti onipele kereje nigba ti olumojuto apo owo ifeyinti, ti an pe ni PFC yoo maa toju owo ati awon ohun ini miiran ti a fi owo ifeyinti ra lai si ifoya Kankan.

**12. Awon ilana wo ni igbimo alase eto ifeyinti ni nigeria la sile lona ti owo t'o wa ni ikawo eleto idawo ifeyinti ko fi ni yingin?**

Eto itopinpin ati idari t'o munadoko wa ti igbimo alase eto ifeyinti ni Nigeria la kale nipa titopinpin lojoojumo, ohun ini ati igbese ipinnu t'o n waye lori okoowo Eleto Idawo Ifeyinti. Igbese naa yoo je ki gbogbo ipinnu ati idawole t'o ro mo eto yii wa labe ofin ati isediwon okoowo ti Igbimo Alakooso Eto Ifeyinti la sile.

**13. Nje eto idaniloju kan wa lori ipese aabo awon ohun ini t'o wa l'abe ilana idawo ifeyinti onipele kereje?**

Bee ni ajo PFC, ti pese aabo t'o daju lori gbogbo ohun ti o wa ni ikawo re,koda, bi kobo ba poora, ajo naa yoo san an pada.

**14. Se owo ti a da ni abe ilana idawo owo ifeyinti onipele kereje ni ere ninu?**

Bee ni, o l'ere ninu. ajo PFA n fi gbogbo owo ti a da labe ilana idawo owo ifeyinti onipele kereje sowo. Ggbogbo ere t'o ba si ti ibe jeyo ni a maa fi kun owo ti eni to n kopa labe ilana idawo naa ti da.

**15. Nje, won n yo owo ori ninu owo ti a da l'abe ilana idawo ifeyinti onipele kereje?**

Rara o, gbogbo ere, ipinwo, oko owo, ele ati awon owo miiran to je yo lori owo to wa labe ilana idawo ifeyinti onipele kereje ko l'owo ori sisan ninu rara.

**16. Nje mo le yan iru okoowo ti mo fe ki won fi owo mi se?**

Rara, ko seese. Ajo PFA nikan ni ofin faaye fun lati yan idi okoowo ti a le da owo ifeyinti si, ti o si gbodo wa ni ibamu pelu ofin ti igbimo Alase Eto Ifeyinti ni Nigeria (PenCom) gbe kale lori fifi owo ifeyinti se oko owo.

**17. Se iyato wa ninu ilana idawo ifeyinti onipele kereje ati eto ifowopamo si ile ifowopamo olokoowo?**

Beeni, iyato wa laarin ilana Idawo Ifeyinti Onipele Kereje ati fifi owo pamo si ile ifowopamo olokoowo. Idi ni pe, osoosu ni eni t'o n dawo s'apo Idawo Ifeyinti Onipele Kereje yoo maa gba owo bi eni ti o n gba owo osu leyin ifeyinti lenu ise nigba ti ile Ifowopamo Olokoowo le fun ni lowo nigbakuugba ti eni to ni owo ba ti nilo owo re.

**18. Owo ti o kere julo ti eniyan le da labe ilana idawo ifeyinti onipele kereje?**

A ko la iye kan pato sile, ti eniyan le fi bere eto idawo ,tori pe  alara lo mo bi ohun ti fere tabi wuwo si. Sugbon ti owo eni ba po,o daju ,bee ni owo ifeyinti olosoosu naa yoo se po si

**19. Igba meloo ni eniyan le dawo labee ilana idawo ifeyinti onipele kereje?**

O le je ojoojumo, osoose, osoosu tabi bi o ba se r'orun fun eni ti o n dawo, leyi ti o gbodo wa ni ibamu pelu ofin igboworin ni Orile ede yii.

**20. Ona wo ni mo le gba dawo labe ilana idawo ifeyinti onipele kereje?**

Nipa sisan owo taara si ile ifowopamo olokoowo tabi fifi ero ayelujara sanwo yala ni ile ifowopamo olokoowo tabi nipase awon asoju eto igboworin ni Ilana ti ile ifowopamo ijoba apapo (CBN) la sile.

**21. Nje ondawo labe ilana idawo ifeyinti onipele kereje le fi owo re t'o wa ni akosile labe eto idawo ifeyinti se oniduuro ya owo?**

Ko seese. A ko le fi owo to wa labe eto liana idawo ifeyinti onipele kereje se oniduuro eto iyawo.

**22. Se ondawo le ti ipase iye owo t'o ni ninu apo idawo ifeyinti ya ju iye owo t'o ni ninu idawo ifeyinti onipele kereje ki o si maa san an pada diedie?**

A ko faaye gba iru eto iyawo bee. Ondawo ko le ya koja iye ti o ni tori pe ofin Eto Ifeyinti Alatununto Odun 2014 (PRA 2014) f'ofin de irufe iyawo bee?

**23. Bawo ni mo se le ri owo mi ti o wa l'abe idawo ifeyinti ilana onipele kereje gba?**

Ona meji ni ondawo labe ilana idawo ifeyinti onipele kereje le ri owo re gba:

a) nipase gbigba owo ti isele ojiji tabi airotel, tabi

pajawiri ba de ba eniyan.

b) Gbigba owo ifeyinti.

**24. Ki ni gbigba owo ni ojiji abi airotele?**

Gbigba lara owo ti a da sabe ilana idawo ifeyinti onipele kereje ati ele t'o wole si ori owo ti a da nipase okoowo, nigba ti inawo ba fe'ju mo ondawo labe eto ifeyinti sugbon ti ondawo naa ko ti feyin ti lenu ise.

**25. Ki ni gbigba owo ifeyinti?**

Gbigba owo ti ondawo labe eto ilana idawo ifeyinti onipele kereje letoo si losoosu ti o ba ti feyint lenu ise, ni ilana ofin ati eto ti Igbimo Alakoso Ifeyinti (PenCom) la sile.

**26. Bawo ni mo se le gba owo fi gbo bukata airotele?**

Ondawo le gba lara owo re lati fi gbo bukata airotele nipa kiko iwe si ajo PFA gegebi a se la a sile.

**27. Akoko wo ni eniyan gbodo fi d'awo ki o to letoo si gbigba owo fi gbo bukata airotele?**

Ondawo le gba lara owo ti o da labe ilana idawo ifeyinti onipele kereje l'eyin osu meta ti o bere sii da owo labe eto ifeyinti. L'eyin eyi, ondawo letoo si gbigba owo ni ekansoso l'ose ninu owo re t'o seku labe eto idawo naa.

**28. Yoo ti pe to ki n to le gba ninu apo owo airotele?**

A ti pa a lase fun awon ajo PFA pe ki won maa f'ase si eto iyawo bee, ki won si san iye ti ondawo beere fun, o pe tan, laarin wakati mejidinlaaadota (48 hours) ti won gba iwe ibeere iyawo.

**29. Kini o maa sele si ondawo labe ilana idawo ifeyinti onipele kereje ti o ba ri ise olowo osu?**

Ondawo, ti eto idawo re  wa labe Ilana Idawo Ifeyinti Onipele Kereje,gbodo tete fi anfani ise sise ti o ri to Ajo Alakooso Eto Owo Ifeyinti leti.,ki won le yi eto Idawo re si ti alajoda ( eto idawo laaarin agbanisise ati osise.). Ondawo gbodo fi eto idawo re sile bi o se wa,ki won le yi eto re pada si Eto Idawo Alajoda laaarin awon agbanisise ati osise.

**30. Yoo ti pe to ki ondawo ifeyinti onipele kereje to feyin ti l'enu idawo?**

Ondawo labe ilana idawo ifeyinti onipele kereje le feyinti lenu idawo ti o ba ti pe aadota odun (50 years), tabi ti o ba ni ailera ti ko si le se ise mo. Sugbon o, Ondawo le sun ojo ifeyinti re l'enu idawo koja aadota odun ti o ba fe.

**31. Bawo ni mo se le gba owo mi l'eyin ifeyinti?**

Ti Ondawo ba ti feyinti,yoo bere si i gba owo ifeyinti

yala nipase eto igbowo eleseese (PROGRAMED WITHDRAWAL) tabi nipa ilana adeun ti o se pelu ile ise madaamidofo (LIFE ANNUITY)

**32. Kini programmed withdrawal?**

Eto igbowo eleseese je irufe ilana owo sisan ti ondawo ilana Idawo Ifeyinti Onipele Kereje fi maa n gba owo ifeyinti l'odo Ajo PFA ni igba de igba, paapaa julo, ni osoosu tabi ni osu meta.

**33. Kini Annuity?**

Eyi ni ona gbigba owo ifeyinti ni ipase ilana adeun ti Afeyinti se l'odo ile ise madaamidofo. Ona gbigba owo yii fun ondawo ni idaniloju gbigba owo ifeyinti re lore koore leyin ti o ti feyintilenu ise, niwon igba ti o ba wa laye.

**34. Odun meloo ni afeyinti ni liana madaamidofo ni idaju lati fi gba owo ifeyinti?**

Odun mewaa (10 years) gbako ni afeyinti ni idaniloju pe ohun yoo fi ri owo ifeyinti gba lodo ile ise madamidofo leyin ti o ti feyinti lenu ise. Sugbon ti eni ti o ti feyinti ba ku ki odun mewaa to pe, awon ti o fi oruko won sile ninu iwe adeun eto Ifeyinti re ni yoo gba owo fun iye odun to ku ki odun mewaa fi pe. Ti afeyinti ba wa ku leyin odun mewaa ti o ti n gba owo ifeyinti labe ilana eto yii, awon molebi ko letoo si owo

kankan mo ni gbigba.

**35. Nje eto kan wa nile lori iye owo t'o ku,ti ondawo ilana idawo ifeyinti ba ku?**

Ti olojo ba de, awon ti won letoo gbigba owo ondawo (oloogbe) labe ofin ni yoo gba owo to ku nini apo ifowopamo oloogbe ni odo ajo PFA.

**36. Nje mo le kopa ninu eto idawo ifeyinti l'enu ise onipele kereje ti mo ba ti feyinti n'ile ise olowo osu ti mo wa?**

Rara o.ko seese.sugbon a le yi eto idawo ifeyinti onipele kereje si Eto Idawo Ifeyinti Alajoda olorananyan (idawo laaarin agbanisise ati osise).

**NATIONAL PENSION COMMISSION**

Plot 174, Adetokunbo Ademola Crescent Wuse II, P.M.B. 5170 Wuse, Abuja, Nigeria.
Email: info@pencom.gov.ng
www.pencom.gov.ng
Tel: +234 (9) 4603943, +234 902 979 7837